# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**Oṣù Kẹ́rin, Ọdún 2025**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

**AGBÁRA GBỌDỌ̀ PÀRỌ̀ ỌWỌ́ OṢÙ KẸ́RIN, ỌDÚN 2025**

1. **Agbára mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù,**

‘Torí ó w’ẹ̀ṣẹ̀ mi nù,
Mo sì mọ̀ pé ìhìn Rẹ̀ lí ayọ̀,
Ó sòkùn mi di’mọ́lẹ̀.

Ègbè
Agbàra mbẹ, Agbára t’ó n ṣiṣẹ́ ìyanu
Agbára mbẹ, Agbára tí ó nwẹ̀ wá mọ́,
Mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù.

2. Agbára mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù,

Ó gbà mí lọ́wọ́ ẹ̀bi,
‘Gbàtí mo k’ẹ́rù ẹ̀ṣẹ̀ mi tọ̀ Ọ́ wá,
Ẹ̀jẹ̀ Rẹ sì wẹ̀ mí mọ́.

3. Èmi mọ ire t’ẹ́jẹ̀ ná nṣe,

Ó ti sọ wá di titun,
Nípa ẹ̀jẹ̀ Rẹ iyebíye nà,
Mo di mímọ́ títí láí.

1. **Nípa ìfẹ́ Olùgbàlà**

Kì y’ó sí nkan
Ojú rere Rẹ kì padà
Kì y’ó sí nkan;
Ọ̀wọ́n lẹ̀jẹ̀ t’ó wò wá sàn;
Pípé l’èdìdì ór’ọ̀fẹ́;
Agbára l’ọwọ́ t’ó gba ni

Kò lè sí nkan

2. Bí à wá nínú ìpọ́njú,
Kì y'ó sí nkan;
Ìgbàlà kíkún ni tiwa,
Kì y'ó sí nkan
Ìgbẹ́kẹ̀lé Ọlọ́run dùn;
Gbígbé inú Krístì l'érè
Ẹ̀mí sì nsọ wá di mímọ́,
Kò lè sí nkan

3. Ọjọ́ ọ̀la yó sì dára
Kì y'ó sí nkan
'Gbàgbọ́ lè kọrin n'nú 'pọnjú
Kì y'ó sí nkan
A gbẹ́kẹ̀lé 'fẹ́ Bàbá wa;
Jésù nfún wá l'óhun gbogbo
Ní yíyè tàbí ní kíkú;
Kò lè sí nkan.

## **ỌRỌ̀ AGBÁRA**

1. Gbogbo ẹ̀kún-omi òkùnkùn tí wọ́n yàn lòdì sí igi ìdílé mi yóò gba itìjú lónìí, ní orúkọ Jésù.
2. Gbogbo obìrí ibi nínú ẹ̀jẹ̀ ìran mi tó n yọ Ísráẹ́lì mi lẹ́nu yóò kú lónìí, ní orúkọ Jésù.

3. Lónìí, nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, èmi yóò rí òpin àwọn agbára tí wọ́n yàn láti da ayé mi láàmú nítorí àṣìṣe àwọn òbí mi, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo agbára òkùnkùn láti ilé bàbá mi, tó n jí àwọn ohunrere lọ́wọ́ mi, gbọ́ Ọ̀rọ̀ Olúwa, iná Ọlọ́run Èlíjàh yóò jó ọ run lónìí, ní orúkọ Jésù.
5. Ohunkóhun tí ọ̀tá ti gbékalẹ̀ lòdì sí ayànmọ́ mi, gb'iná báyìí, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo májẹ̀mú ìpọ́njú àti ìrora ìrandíran nínú ayé mi yóò fọ́ lónìí nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
7. Iná Ọlọ́run, àrá Ọlọ́run, lé ìrora àti òṣì kúrò nínú ayé mi báyìí, ní orúkọ Jésù.

<u>**ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ**</u>

**1 Kọ́ríntì 15:57:** Ṣùgbọ́n ọpẹ́ ni fún Ọlọ́run, ẹnití Ó fi ìṣẹ́gun fún wa nípa Olúwa wa Jésù Krístì.

**2 Kọ́ríntì 2:14** Ṣùgbọ́n ọpẹ́ ni fún Ọlọ́run, ẹnití nyọ ayọ̀ ìṣẹ́gun lórí wa nígbàgbogbo nínú Krístì, tí Ò sí nfi orun ìmọ̀ Rẹ̀ hàn nípa waníbigbogbo.

**Ìfihàn 12:11** Nwọ́n sì ṣẹ́gun rẹ̀ nítorí ẹ̀jẹ̀ Ọ̀dọ́-Àgùntàn ná, àti nítorí ọ̀rọ̀ ẹ̀rí wọn, nwọn kò sì fẹ́ràn ẹ̀mí wọn àní títí dé ikú.

**Kólóssè 2:14-15:** Ó sì ti pa ìwé májẹ̀mú nì rẹ́, tí ó lòdì sí wa, tí a kọ nínú òfin, èyítí ó lòdì sí wa: òn li Ó sì ti mú kúrò lójú ọ̀nà wa, Ó sì kàn á mọ́ àgbélèbú. Ó sì ti já àwọn ìjọba àti agbára kúrò lí ara rẹ, ó sì ti dójútì wọ́n ní gbàngbà, ó nyọ ayọ̀ ìṣẹ́gun lórí wọn nínú rẹ̀.

**Rómù 8:37** Ṣùgbọ́n nínú gbogbo nkan wọ̀nyí, àwa ju ẹnití ó ṣẹ́gun lọ nípa ẹnití ó fẹ́ wa.

**Jòhánnù 16:33** Nkan wọ̀nyí ni mo ti sọ fun nyín tẹ́lẹ̀, kí ẹ̀yin kí ó lè ní àláfíà nínú mi. Nínú ayé, ẹ̀yin ó nì ìpọ́njú; ṣùgbọ́n, ẹ túјúká; mo ti ṣẹ́gun ayé.

**1 Jòhánnù 5:4-5** Nítorí olúkúlùkù ẹnití a bí nípa ti Ọlọ́run, o ṣẹ́gun ayé: èyi sì ni ìṣẹ́gun tí ó ṣẹ́gun, àní ìgbàgbọ́ wa. Tani ẹnití ó ṣẹ́gun ayé, bíkòṣe ẹnití ó gbàgbọ́ pé Ọmọ Ọlọ́run ni Jésù ìṣe?

## <u>ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ</u>

**<u>Ìjẹ́wọ́: Orin Dáfídì 91</u>**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ìwọ agbára òkùnkùn tó njá àwọn ẹ̀rí mi bọ́, Ọlọ́run, dìde, já wọn wálẹ̀, ní orúkọ Jésù.
4. Aṣọ àjèjì tí wọ́n rán fún mi, bọ́ s'ọ́rùn ẹnitó ni ọ́, kí o sì jó wọn run, ní orúkọ Jésù.
5. Agbára òkùnkùn tó nfi àdúrà mi rẹ́rìn, kígbe kú, ní orúkọ Jésù.
6. Àìsàn burúkú ní bèbè àwọn alàjá mi, pa àwọn tó ni ọ́, ní orúkọ Jésù.
7. Olúwa, fi àwọn iṣòro tí ó tóbi ju àwọn ọ̀tá mi ta wọ́n lọ́rẹ, ní orúkọ Jésù.